**Akiyesi**

A nfe asoju ni awon ilu wonyi: Ibadan, Jos, Ondo, Ilesha, gbajr Ogbomosho, Saki, Kaduna, Ijede, Oyo, Ile-Ife Zaria, Gbogan, KABBA, Otta, Ilaro, Aba, IKIRE kowe si Olotu 16, Bamgbose Street. Phone 21985

# IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**WANTED**

One Advance Apprentice Printer and two Apprentice Printers.

Apply to:-

Manager
Modupẹ Prg. Press
16, Bamgbose Street
Lagos.

VOL. IV No. 189 MONDAY JANUARY 9 — JANUARY 15 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Ijoba Apapo pase wipe ki Asoju ile Faranse jade kuro ni'le Naijiria

IJOBA ILE Naiijiria pase wipe, ki Asoju awon Faranse ti oruko re nje Raymond Offroy ti o wa nile Naijiria gegebi ỌRẸ LATI MA ṢE ALAGBAWI LARIN IJỌBB ILE NAIJIRIA ATI IJỌBA FARANSE ATI LATI MA ṢE ATUNSE LARIN AWỌN IJỌBA MẸJẸJI BI EDEKOYEDE BA FẸ ṢẸLẸ KI O GBE IGBA ẸRU RẸ, ki o si jade patapata kuro nilẹ Naijiria ki o to to wakati mejidiladọta.

Ohun ti o fa sababi yi wa ni wipe, nigba mẹta toto ni Ijọba Faranse fi ẹmi awọn ara Ilẹ Afrika wu ewu jamba ẹtu Oloro (Atomic Bomb) laibikita fun ohun-kohun ti o le ti idi rẹ bọ. Bi a ba tilẹ sọpe ti akọkọ ṣeṣi ni, tigba keji nkọ? Ijọba Naijiria ke ke, ke, Faranse ri on 'ko gbọ, Gẹẹsi wi, Amerika wi pẹlu, sibẹ nwọn ni awọn ko mọ ẹniti o ku.

Bi ẹtu oloro Atom, ba jẹ ikan ere fun Faranse iku lo jẹ fun awa ti o ngb ilẹ Afrika, nitoriki a le ma ba ara wa gbe ni alafia ni Naijiria ṣe gba lati ba Faranse ṣe ọrẹ, ṣugbọn bi ọrẹ ko ba ṣeṣe mọ, ẹṣẹ, a o jẹun wa ni ọtọtọ. Ki nwọn gbe igbe wọn lọtọtọ. Iwọnyi ni ohun ti o ṣẹlẹ, ni ekoko ti Ijọba nṣe igbimọ nipa ọrọ ẹtu oloro ti Faranse yin nigba kẹta.

Awọn Igbimọ ti de ni agogo mẹsan eyi si ni ipinu ti nwọn ṣe. Ọkọ Ofurufu Faranse ko gbọdọ gunlẹ silẹ Naijiria mọ, bẹni ọkọ oju omi wọn ko gbọdọ gunlẹ si ilẹ Naijiria mọ. A gbọ wipe gbugbo owo ati dukia Faranse ti o mbẹ nilẹ Naijiria fẹrẹ to £100 million.

Ohun ti o fa sababi yi wa ni pe Ijọba Faranse ṣe aibikita fun ẹmi awọn enia dudu ti o mbẹ nilẹ Naijiria Ijọba rope nigbigbe ẹsẹ bayi, ajumọṣe pọ ti o mbẹ larin ilẹ Naijiria ati Faranse yio duro. Ijọba Naijiria ko ni Aṣoju nilẹ Faranse.

## Munisiba fe ki Ijoba se ofin owo Ile hihaya

Ninu Ipade oṣoṣu ti awọn Igbimọ Town Council ma nṣe, nwọn ṣe ipinnu lati ke si Igbimọ Alapapọṣe wipe ki nwọn ṣe Ofin le ori Ile hihaya, ki nwọn da iyele owo ti nwọn o ma san le ori Yara kan ni Ilu Eko nitoripe Ogunlọgọ awọn ti o nhaya ile nwọnyi jẹ awọn Oṣiṣẹ ti wọn ngba Owo poku nibi iṣẹ wọn wọn, ati pẹlu wipe, ko nṣe gbogbo awọn Oṣiṣẹ na lo nṣiṣẹ labẹ Ijọba, omiran si mbẹ l'abẹ enia dudu Omiran wa labẹ Oyinbo Onisowo tiko lagbara lati san owo giga bi ti Oyinbo.

Nwọn tun ṣe ipinnu pe, awọn opopo ọna ti o ti wa ri gegebi Opopo ọna ti o wa ri gegebi Opopo Breadfruit, Davies, Portnovo, Market St. ati Pam Church St. kiwọn pa a da ki nwọn fun wọn ni Orukọ miran ninu awọn enia pataki ti nwọn ni orukọ larin ilu Eko.

## Igbimo Egbe Amofin gbogbo Agbaiye se Ipade nla lE'ko

NIBI IGBIMỌ Nlanla kan, ti a ko iti se iru rẹ ri ni Ilẹ Enia dudu ti awọn Ẹgbẹ Amofin Orilẹ ede Enia dudu se l'Eko ni ọsẹ to koja yi. Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa sọ wipe itumọ Ofin ni lati da abo bo Orilẹ ede ati gbogbo ẹniti o ngbe inu rẹ, ati fun ẹtọ Olukuluku.

Ọlọla Tafawa Balewa Olotu Ijọba Ilẹ Naijiria wi pẹlu wipe Ilẹ Naijiria ni Asiwaju gbogbo Orile ede yoku nipa eto Ilu ati eto olukuluku ti mbẹ ni Orilẹ ede Najiria nitoripe eyi ti wa ninu akọsilẹ iwe Iṣelu ilẹ Naijiria, lẹhin eyi Ọlọla Tafawa Balewa wipe ẹtọ olukuluku jẹ ohun ti o kanpa ni orilẹ ede ti o dara, o wa bẹbẹ wipe ki ẹnikẹni ma ṣe fi ẹtọ silẹ lati ma pa lapalapa lori ọrọ ẹtọ Olukuluku ki o ba le ye ọpọlọpọ enia enia wipe ẹtọ ara ẹni yi ba ofin lọ.

Lẹhin ti o ti bi gbogbo awọn enia ti o wa lati orisirisi Orilẹ ede Agbaiye tan Ọlọla Tafa wipe gbogbo ẹniti o wa ni ipo giga ni iṣẹ nla ṣe nipa pipa ofin mọ ati idabo-bo ofin. Siwaju eyi Alagba Adetokunbọ Ademọla Adajọ Agba Apapọ Ilẹ Naijiria ninu ikini kabọ rẹ o jẹ ohun pataki wipe iru Igbimọ yi se ipade Orilẹ ede enia dudu ni akokọ ti o jẹ wipe awa Orilọ ede yi ti gba Ominira ti a si ni iṣẹ pupọ lati ṣe

Alagba Ademọla ẹniti nṣe Alaga Igbimọ yi wipe ó jẹ ohuu pataki wipe iru Igbimọ ti o nja fun ọwọ ara ẹni ati pipa Ofin mọ pejọ pọ lati ṣe asaro lori ọrọ ṣiṣe ofin, ati pipa ofin mọ. Lẹhin eyi Alakoso Igbimọ Asofin ilẹ Naijiria Ọgbẹni Dokita T. O. Elias sọrọ lori iṣẹ nla ti o wa lọrun awọn Asofin ati bi awọn asofin ti ṣe ni lati ma dabo bo olukuluku enia ti mbẹ loriiẹ ede enia dudu.

Awọn Ogbonkangi lọya (lawyer) bi Oloye Rotimi Williams, Ọlọla G. B. A. Coker, Oloye H. A, Davies, Ogbẹni R. A. Fani-Kayọde Agbẹjọro Oba-birin Ilẹ Gẹẹsi ati Oloye Athur Prest ni won joko pẹlu awọn Asofin ati Amofin gbogbo Agbaiye ti wọn si sọ ọrọ iṣiri nibi Ipade yi.

## Lori Owo ko nse lori ijofe



Eniti a nwo ninu Aworan yi ti o gbe Bọlu Alafẹsẹgba dani ni eniti nwọn npe ni George Eastham ti o ti ngba ere Bọlu Alafẹsẹgba fun awọn ẹ g b ẹ kan ti nwọn npe ni New-Castle United.

Nwọn mọ pe ni bi Egbe ti George ba ko idi si, mimọgbaye a ma jẹki awọn ẹgbẹ na bori. Awọn ẹgbẹ miran tun wa ti nwọn jẹ Ọta, sasa ẹgbẹ ninu gbogbo ẹgbẹ lo le bori wọn, ẹgbẹ na ni Leicester City ti nwọn fẹ ba Arsenal Reserves ta pero, awọn Arsenal wa ya George ni £47,500 lọdọ awọn ẹ g b ẹ Arsenal Reserves.

George na ni a nwo nigbati awọn Enia nwo o, nibiti o gbe ndanra wo.

## Petepete T'ana Ni Popa

Lati Owọ:— DELE ATỌLAGBE.

EYI MA POJU O!

Olotu/ ẹku ewu ọdun Keremẹsi ti o koja yi, ẹ si tun ku ewu ọdun titun ti awa ninu rẹ yi. Olorun ko se ọdun labo. (Amin.) Mo si tun ki gbogbo awọn ọnkawe Irohin Imọle pe E ku ọdun ẹ ku iyedun.

Ohun ti oju mi nri ni nkan bi ọdun mẹrin sẹhin jẹ ohun pataki ti o je iyalẹnu fun emi Petẹpetẹ tan ni popa. Kini ki a ti gbọ, kini ki a ti wi, kini ki a ti se ọnu wi pe ọmọ ọdun mejila, metala, tabi merinla ti nloyun wọn si ti nbi ọmọ. Enyin obi awọn ọmọbinrin wọnyi ni mo nba wi. Nibo ni iwọ baba ọlọmọ wa nigbati ọmọ binrin rẹ tabi ọmokunrin rẹ njade kuro ninu ile rẹ ti o si nwọle wa ba nyin ni dede agogo mejila alẹ? Bi a ba se akiyesi iru awọn ọmọbinrin ti ese won dabi ẹiyẹ wọnyi, a o ri wipe bi o ti wọle ni dede agogo mejila alẹ yi, pẹlu Okunrin kan ti on na ko ju ọmọ ọdun medogun lọ ni y i o sin tabi tele e de ẹnu ọna ile rẹ ki o to pada lẹhin ti wọn ti wọn ti se ohun ti wọn fẹ se fun ara wọn tan.

Nigbati ọmọ rẹ nwọ aṣọ 'Bonfo' lati jade ni ojojumọ ti o si tun sampu (Sampoo) irun rẹ njẹ iwọ ko mọ pe ki okunrin le ri ni ọmọ rẹ nse? Boya ni ọjọ keresimesi toko ja yi, ọmọ rẹ dagbere fun iwọ obi rẹ pe on fẹ lọ ra nka ni ile itaja (going ashoping) o si da iwọ obi buruku loju pe o ko fun ọmọ rẹ ni owo kankan tele, kini ẹ ti o ko se ibere ibiti o ti ri owo ti o fẹ fi ra nkan na ni sọbu? Ọmọ rẹ jade niṣoju rẹ, o tun pada wa sile pelu aṣọ olowo iyebiye ti o fẹ fi da aṣọ sitayi (style) tuntun ti anpe ni bonfo. Se bi o ye ki iwọ obi ọmọ yi mọ wipe lọwọ okunrin ara ita miran ni ọmọ rẹ ti gba owo ti o fi ra aṣọ rẹ yi? Nigbati ọmọ rẹ ngba owo lọwọ okunrin nita kini iwọ obi rò wipe yio sẹlẹ lẹhin rẹ? Bi o ba wa se akiyesi pe ọmọ rẹ ti loyun iwọ a wa fa agidi yọ pe nigbawo ni eleyi de kẹ?

WO IYOKU NI OJU EWE KERIN

## Imoran fun Omo Ajasse-po

### Lati Owo:- Omo Egbe Aiye mojuba

### Lagos Branch

O BERE LATI ỌSẸ TO KOJA

Nitoribẹ, Ọtẹ ni ohun ti nsẹlẹ ni Ajassepo, osi yọ ki ẹgbẹ kọkan pe arawọn jọ, ki ọtẹ na kuro nilẹ, ki o masi ogun jija, awa ẹgbẹ yi kọlẹ ki ilu para ilọsiwaju ilu ni anfẹ ninu wa lasd bẹ ẹbẹ ọrọ yi ninu Iwe irohin Imọlẹ fun yin, ki ẹ jọwọ ki ẹ ba wa gba ọrọ yi yẹ wo Oluwa yio tun ile ati ọna Olukaluku se, awa Egbẹ yi ko sọ pe ki ẹniti nse Igbominọa parapọ ko ma se mọ, bẹ sini awa koni ki eniti nse Egbẹ olomi N. P. C. ko ma se mọ, sugbọn nkan ti awa sọ ni pe ki ẹgbẹ kọkan mura lati ma wa Ilọsiwaju fun ilu rẹ, gegebi apejuwe kẹ wo Ilu Eko awọn ẹgbẹ oṣelu pọ nibẹ, sugbọn olukuluko wọn ni ofe rere wa sibẹ, Bẹna si ni Ilu miran papa. Ewo Ilu Ibadan. ẹgbẹ ọlọpẹ pọ nibẹ, ẹgbẹ alakukọ Alakuko pọ nibẹ awọn mejeji nse daca sibẹ na, Ilu miran na bẹ ti ẹnikan ko di ẹnikeji lọwọ, wọn ko di na fun ara wọn. E jẹki a ronu dada, ki a wo bi nkan ti nlọ ẹ jẹki apa ẹ jẹki apa ote ti, ki atun Ilu wa se ki a ni irepọ, ati ki ifọkan bale bawa, torina abe yin pipọ, ki ẹtọ ju ajasse-po kẹ ma jẹki aiẹ ara wa niya, Oluwa ko ma jẹki ajẹ ara wa ni ya o Oluwa yio bo aṣiri ẹnikọkan wa, awa ẹgbẹ yi nsọ ọrọ fun ọmọ Ajassẹ to ba wa nibikibi.

O di igbakan na, ẹo tun ma ka siwaju ni ỌSẸ tombọ

## OWE

Lati Owọ:— BOB DALA (Lagos.)

ARUGBO Eru ki jọ fẹ, otosi ọ b a ki sin igba iwọfa ti kọku ti ko dẹ se aisan ko gbọdọ sọpe ohun ko ni san owo fun Olowo mọ. Bi oni yio ti ri, ọ l a ki ri bẹ mọ, ohun lo mu Babalawo d'ifa Ọrun. Eniti yio jẹun gbọningbọnin yio ti Ilẹkun gbọin-gbọin. Bi o pẹ titi ọdun marun opada bọ wa ku ọla. Suẹn ni Baba iwa ni Aiye yi.

## Awon omo Akeko nse idanwo



Awọn ọmọ Akẹko meji ti o duro ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ti o lọ kọ iṣẹ ẹrọ nipa mọto, ẹnu idanwo ni nwọn wa bi a ti nwo wọn ninu ime yi, enia dudu lo mbẹ lọwọ ọtun, oyinbo lo si mbẹ lọwọ osi.

## Petepete T'ana Ni Popa

Lati Owo:— DELE ATOLAGBE.

EYI MA POJU OJ

O BERE LATI OJU EWE KEJI

O ye ki nko orin kan bayi " Nigbati Q m ọ rẹ nra nra aso Bonfe wale talo so fun, igbati o wa di oyun o fi igbe ta". Enyin Onkawe Irohin Imole mo fe ki e mọ daju pe gbogbo oyun ti awọn agba-iya ti wọn npe ara won ni Sinio Sifisi (Senior Service Men) ti, wọn wa ni ipo giga nibi ise, won a fi owo tan awọn Ọmọbirin wonyi je, won a si so won di alagbere omo. Boya e o bere ibiti awon agba-iya yi ti mọ awọn ọmọbirin wọnyi ri? Ile ijo ti anpe ni ( H o t e l s) ni wọn ti mọ awọn omo na dada. Ibiti won ṣe ti n ba wọn jo pọ, won a tete ibiti won ngbe lowo ara won, a si di wipe ọmọbirin nwa won lo sile wọn lalale

Enyin Obi eti nyin m e l o? E kilọ ile Iju lilọ fun awon omo yin papa julọ awon ti nlọ si ile iwe Ase ti won n wọ jade lati ile ni yio so iru e n i a ti awọn ọmo nyin ẹlẹsẹ tirin mọ. Bi o ba di wipe awọn ọmọ yin l'oyun tan, gbogbo awọn ti won ti nwa tẹlẹ n e ko ni gburo ikankan nino won mo. won a si so Ọmobinrin yin di olori buruku. Nitorina enyin Obi ti ẹ ba fẹ ilosiwaju Ọmọ nyin, ẹ tọju wọn nigbati won wa ni kekere ki won ma ba se epe fun nyin lehin ọla.

Mo gbagbọ pe awọn Alagbatọ mọ ọmọ toju jo awọn Obi papa lọ, nitoripe awọn Obi miran ko lagbara lori omo won bi Alagbatọ ti yio fi ọpọlọpọ i-ya je ọmọ ra ti ki gbọ ọro si Obi won lenu.

E o ma gbadun mi to nigbamiran Odigbo se!


## Latest Remedy

**Why retard and Relax ? Defy Indifference Subjugate Rivals and Work With Pleasure**

By taking Haury:—

**"Glutamic Acid Tablets"**

Enteria coated tablets are a peerless tonic for body mind and nerves; they give energy for tireless and deep concentration and exercisons. It is an important tonic for STUDENT, with whom it is an actual amplification and actualisation of their personality, they become open in mind, lose their timidity and shyness. Their efficiency in school is remarkably increased. Adults become more balanced, energetic, active and very enthusiastic to master their problems with

Ease & Comfort:

Price 12s. 6d. Postage 2/6

Sole Agents:

Waterloo Medicine Stores,

Continental Medicine Specialists

8, Palm Church Street P. O. Box 333

Lagos Nigeria. Phone: 22878


## Akiyesi Pataki

Eyin Q m ọ Iya mi, E mase fi ẹmi yin wu Iṣegun Alakala isegun Osho, ati A j e Ṣile kan pere 1s. Pẹlu Stampu Sisi 6d fun Ida esi pada.

Fi Owo ranse si:— D ABIODUN ESQ. Ni
P. O. Box. 444 IBADAN.

Tete ta tire ki o to tan, enyin Q m ọ Iya mi ijafara lewu ẹ ma se fi ẹmi yin wu ewu,


Printed and Published by ODUPE PRINTING PRESS
16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21985. Olotu: E. A. Adeniji
51, Tejuoso Street Suru-Lere YABA

FUN OWO IROHIN IMOLE ỌDUN KAN
EKO: Ṣile merin ati kobọ merin (4/4d)
Ilumiran ni Naijiria ati Oke Okun:-
Ṣile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/-6d)


## Awon enia meji je Oye nilu Eko

Eko:- Awon Musulumi ti nwọn wa ni Mo ṣ a l a s i Jimoh ti Ilu Eko, fi awọn enia meji nwọnyi je oye fun awọn Musulumi Eko, orukọ won niwonyi:- Oloye Abudu Lasisi Ojikutu, ẹnikeji si ni Oloye Alhaji Laguda.

Ajeji enia ka le wọ ilu ki odile ma mọ, iyen ni wipe, a kole fi emikẹni jẹ oye nilu Eko, ki ọba ilu ma mọ Nitorina ni gere ti nwọn je oye na tan ninu Mọsalasi Jimọh, Oloye A. B. A k i y e m i, ati Baba Adini ti ko awon ijoye titun nwọyi lẹhin lati lọ won han fi Ọba wipe ohun ti ti riyi.

Awọn ero dabi omi ati fon ati lu, ti gbogbo won jo lọ si afin oba, Eko. Ọba Eko si fi tayo tayọ gba nwọn ni alejo. Bi o ti lẹ je wipe ọ d ọ m ọ d e ni awọn ijoye mejeji na, bi enia ba ri won Alufa nla kan ni yio pe won. Ojikutu a t i L a g u d a oye na yio mo nyin lori o Amin.

## IDIJE IDIJE IDIJE

A fi eyi kede fun awọn Okawe Irohin jakejado gbogbo awọn ọmọ karọ-O-jire agbaiye pe ante:— Idahun ti o yanju rekete fun awon ibere wọnyi ki ẹ fi eyiti ṣe ti Bibeli ṣe ti Bibeli ki e si fi eyiti ṣe ti ilu ṣe ti ilu. Ẹnikẹni ti o ba si bori ninu gbogbo ibere yi yio gba E b u n ponun kan sile-kan (£1 : 1/-).

IBERE NA NI WỌNYI

1. Ọna wo ni Ọlọrun gba fi ironu re han awọn ọmọ enia
2. Ona kansoso wo ni ẹkọ Bibeli fi san ju?
3. Ni Ilu wo ni wọn gbe bi Gomina Ilẹ Naijiria ti o ṣeṣẹ jẹ si?
4. Ni ọdun wo tabi ojọ wo ni iwe Irohin Imọlẹ kọkọ jade ni Ilu Eko?
5. Ilu wo ni wọn ti nlu ilu ti ẹnikan si ntumọ rẹ lasiko Ominira ti ọmọ Oba Alexsandra wa si Eko?
6. Kinni o nfi ilu na wi?
7. Igba wo ni o daju pe Bibeli le pẹ da?
8. Kiniṣe ti awọn ọlẹṣẹ fi korira Bibeli?
9. kini ohun pataki ti o ṣelẹ ni ojọ kejidilogbon oṣu keta ọdun 1958?
10. Tani ẹniti o le mu nkan ijinlẹ Ọlọrun wa si ọkan enia?

AKIYESI:- Idahun ibere yi yio pari ni gbigba ni ojọ kerindilogun oṣu Kini ọdun 1961. Ko idahun rẹ ki o han rekete, ti ẹniti ko ba han a o fa ya ni, ki o si mọ daju wipe ko ni ipa ninu Idije na, ti ẹniti o ba dahun mewẹwa pe, ti o si gba ni a o tẹ jade ninu iwe Irohin I m ọ l ẹ yi, a o si fi ponun kan sile kan (£1 : 1/-) Postal Order ranṣẹ si. A ko kọ ọmọde tabi agbalagba. Fi Stampu Tọrọ ranṣẹ fun gbigbe ponun kan sile kan ti o ba jẹ pada iṣọ. Ge ibiti Idije yi gbe wa ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stampu Tọrọ rẹ Enikeni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ ti ko si fi Stampu Tọrọ si ti o ba jẹ owo na a ko ni fi ranṣẹ si, a ko si ni f u n ni Stampu rẹ pada.

Oruko ____________________

Ibugbe ____________________

____________________

Iṣe ____________________

Ojo Ori ____________________

Fi i d a h u n ibere rẹ yi ranṣẹ si:—

OLOTU IROHIN IMOLE
16 BAMGBOSE STREET LAGOS